**Owe**

Adiẹ iba f'ọko, iba f'aṣan ṣe ọkan. Imado iba ṣe bi ẹlẹde a ba'lu jẹ. Eru iba f'ọba, enia ko ba ti ku ọkan.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN-KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

Enia ma jeki t'enia sunwọn, t'eni ma sunwọn ko ni gbọ. Apa ọmọde ko le ka igi Ose, ylo ma doyika.

VOL. XII No 698. LAGOS, SATURDAY OCTOBER 22, — OCTOBER 28, 1960. KỌBỌ MEJI (2D)

# ERO YA WA WO! WOMI-WOMI NI OKE GBEREFU PELU OMIRAN ASUN MA DIDE.

Okun Apẹṣẹ - Irohin ko to afojuba ni iran orişirişi ti o wa ni Afihan ti awọn Ijọba Apapọṣe ilẹ Nigeria nṣe aṣepari rẹ loni l'ọna Okun Alasia nilu Eko, (Exhibition Centre).

Bi enia ba ni on fẹran iran ni wiwo, awo jatọ s'aya ni oniruru afihan ti o wa ninu awọn ile afihan na. Bi t'ọkọ-t'aya ba jijọ lọ sibi afihan yi, ti nwọn ba wọle de ibi iworan, ọtọ-tọ ni olukuluku ma pada sile nitoripe iran wiwo ko ni jẹki nwọn ri ara wọn mọ. Ọpọlọpọ awọn ọmọde l'o ti sọnu lẹhin obi wọn.

Bi enia ba bẹrẹ si woran yi lati owurọ titi di agogo mẹwa alẹ. Boya ni oluwarẹ le de idamẹji ninu ile afihan na. Bi awọn Ijọba Ila-orun ti nfi han wipe ilu wọn ni o dara julọ bẹni awọn Ijọba Iwọ - orun ati Ijọba Ariwa, l'Oke - Ọya paapa nfi ti nwọn gbega si arawọn.

Awọn ile Onişowo gbogbo l'o ni kini şubu lu awọn. Irohin ko to afojuba ni iran wiwo ibẹ, ş'eranwo gbe boroki ... Omiran sun ko le ... Kiniun mba ọmọde şe ... Wọmi - wọmi nwọ inu omi lori oke gbẹrẹfu, Ere enia ngun kẹkẹ-ologere.

Bi enia ko ba wo iran yi iran wiwo oluwarẹ din ọkan laiya.

## Olotu Ijoba Dakan lo Si Ilu Re

EKO - Olotu ijọba Apapọṣe, Alhaji Sir, Abubakar Tafawa Balewa, gba iṣe ipe lati ọdọ awọn Alakoso ọkọ Reluwe lati wa wọ ọkọ Reluwe ti yio kọkọ rin ọna titun ti nwọn şẹşẹ şe lati Bọrọnu lọ si ilu ti nwọn npe ni "Tafawa Balewa" lagbegbe ilu Bauchi,



Ilu na si jẹ ilu Olotu ijọba Apapọṣe, o dakan lọ lọjọ Jimọ ana, yio si pada de lọjọ Satide, ọjọ kọkandi-logbọn oşu October 1960.

## Enito Gbada-modi Oye Iwe Mimo Wewon

IBADAN - Ọgbẹni Vincent Agpofure Okwendo, ti o jẹ ọmọ ogun ọdun lọjọ ori rẹ ni a gbọ wipe o lọ f'iiwe adamọdi oye iwe mi mọ (Wo iyoku loju ewe kẹjọ)


# ELECTRICITY CORPORATION OF NIGERIA

## Press Release

## NIGERIANISATION OF THE LONDON OFFICE

The Board of the Electricity Corporation at a meeting held on 24th September, 1960, endorsed the action taken by the Chairman, Professor Eni Njoku, in issuing his Press Release on the question of posting a Nigerian to the Corporation's London Office and deplored the action of certain sections of the Press in questioning the Chairman's previous statement which did in fact correctly represent the Board's views.

The Board re-affirmed that although the posting of a Nigerian officer to its London Office was part of the Nigerianisation Policy of the Corporation, it was not the intention that such officer should take charge of that office forthwith but rather that he should understudy the Resident Engineer, who performed the dual function of Liaison officer and Engineer at present in-sofar as the Liaison officer's duties were concerned.

15th October, 1960.

# ISE IYANU ATUNBI

(Lati Qwọ John Awojulugbe)

Niwọn ogorun ọdun sehin igbagbọ ti a ni ninu Onigbagbọ ni awọn iṣẹ iyanu nitotọ. Sugbọn lọjọ oni, igbagbọ ti a ni ninu awọn iṣẹ iyanu ni otitọ Igbagbọ.

Nigbati a bi Jesu Kiristi s'ode aiye awọn iṣẹ iyanu ti o nṣe nya awọn enia lẹnu.

Ṣugbọn lọjọ oni ẹwẹ, ani iṣẹ iyanu ninu ẹmi gegebi iṣẹ pataki ti Jesu ti fi ẹmi rẹ sile fun ki iṣe larin Ijọ Kiristi nikan, tiṣ de awọn ijọ miran ti o nsin ẹsin miran pelu.

Iru awọn iṣẹ iyanu ti a ni ju pataki lọjọ oni niwọnyi; Aripe ọpọlọpọ Omuti-ti di ẹniti ko mu ọti mọ. Ọpọlọpọ alagbere ti di ẹni mimọ, awọn opurọ ti di olotitọ, awọn apania ti di ẹni ti o yipada di ẹni rere.

Awọn ti o ti jẹ eni ti o ti nsin ẹsin gan tọkan-tọkan, ati awọn onigbagbọ pataki si ti di ẹniti o tun ntapa si iṣe Ọlọrun.

Ti enia ba ku sinu ẹṣẹ oku, o si ku, ki a gba gbọ pe o ku ofoju ni, ki a si gba pe ofoju ninu ẹmi ni. Ṣugbọn ti a ba tun tun bi, atunbi ki o le riran ninu ẹmi ni, ṣe Ọlọrun fi abo gbogbo rẹ bo wa loju ni, ko si fẹ ki a ku sinu ẹṣẹ. Ẹ ma ṣe jẹki iṣẹ iyanu yi o ba yin lẹru, nipa pe awọn enia ti Ọlọrun ti da ni gba lailai nipa ọna ti Ọlọrun, ti da wọn ni ẹda tuntun ninu Jesu Kiristi. Atun wọn bi, ki si nṣe ninu eso ibaje, ṣugbọn ninu eyiti kole baje lati inu ọrọ Ọlọrun.

Nisisiyi, iṣẹ iyanu atunbi kiṣe iyipada ti o de ara, tabi lile emi eṣu kuro lẹran ara, ki si ṣe ẹkọ abini bi, ki ṣe ẹmi atunraṣe, bi ko ṣe ẹmi titun lati inu ẹmi mimọ. Ẹmi titun ninu ọmọ enia ni ibẹrẹ ere ije titun pelu.

Nje bi atunbi ba jẹ otitọ larin ọmọ enia, paapa larin awa onigbagbọ, o jẹ wipe o wa larin Irin ẹni kọkan wa.—Awọn ohun ti o ti ṣẹlẹ, o wa ni ipamọ lọdọ Ọlọrun. Ọmọ enia le ri oye atunbi, ki o si mọ o lara, ṣugbọn ki ṣe ohun ti a le fi sere, fun awọn enia wo, nitoripe ki iṣe ọgbọn inu iwe. Ako nidi akọnṣe rẹ larin eyi ti a le gbe iwadi le lori lati la idi rẹ ye ni.

Enia ti a tunbi jẹ iṣẹ iyanu ti o ni ẹmi, o dabi igbati enikan di bibẹrẹ shoji rẹ ti o si jade wa.

Pataki idi atunbi ninu onigbagbọ ni igbagbọ, pataki idi iṣẹ atunbi ni ẹmi ti a tunbi, nje atun le tun enia bi nigbati o ti dagba ? dajudaju, bẹni ẹranti ẹlẹṣẹ ti o di ẹni mimọ, awọn ti o ti gbogun ti iṣẹ Ọlọrun ti o tun pada di oniwasu. Ṣugbọn gbogbo orirun wọnyi ni ati ka ninu iwe ọrọ Ọlọrun.

Adura mi nipe gegebi ati di orilẹ-ede ninu ominira titun yi, ki Ọlọrun jẹki ẹniti ko ti di atunbi ninu Oluwa ki o di atunbi.

Gegebi ọdun ti npari lọ yi ti a di atunbi ninu igbagbọ Kiristi, ki a ranti gegebi awọn aposteli ti nṣe ati ẹgbẹgberun awọn ti o gba jesu. Ki ẹ jẹki a ripe, iṣẹ iyanu Atunbi yẹn ti wa ni iṣẹ. Ẹ jẹ k'agbagbe awọn ohun ti o kọja lọ, ki a si ranti eyi ti a bẹrẹ si ni ṣiṣe lọjọ oni, ki a bẹrẹ si wa ọna atunbi yẹn gan.

Ni ọsẹ to mbọ ao kọ nipa kini awọn Heberu fi silẹ fun gbogbo agbaiye ?

# Oba Obinrin Be Ile Ere Nla Wo Nilu Oyinbo



Aworan Alaiyeluwa Ọba Obinrin Elizabeth Kej tilu Oyinbo Gẹsi pẹlu Ọlọlajulọ Ọkọ rẹ Ọmọb Philip ni a nwo yi nigbati o lọ bẹ ile ere nla (Ol Vic Theatre) wo nilu Oyinbo.

Alaiyeluwa Ọba Ọbinrin na l'o ran Ọlọla-n Ọmọba Alexandra wa ṣ'oju rẹ nigba Ominira w tilẹ Nigeria, ti Ọmọba Alexandra na si pada ilu rẹ ni alafia l'owurọ ọjọ Monday ọsẹ yi.

## Baba Egbe Ile Igbimo Nla Nilu Oyinbo



Ọgbeni J. C. Achara ti ise ẹgbẹ Ile Igbimọ nla apapọse ti ti Nsuka. Aṣoju Ila-Orun nilu Oyinbo ni o nki Dr. Nnamdi Azikiwe, Baba ilẹ Nigeria, nigbati o de ilu Oyinbo lati wa oṣiṣẹ fun ilewe giga

## Iku D'oro Ramonu Atanda L'ologbe

(O bere loju ewe keji)

Babalawo aku, Oniṣegun ar'ọrun, iku apa Adahunṣe, iku to pa Ramọnu Atanda, ọmọ ilu Abẹokuta l'adugbo Oja Agbo, oro l'o da. A fi iwosika w'a yi ki awọn ẹgbẹ rẹ ku afẹku ẹni wọn, a ki awọn ọrẹ rẹ pataki Ọgbẹni Layiwọla Amọdu, ti o jẹ ọrẹ kori - kosun pẹlu Ologbe na ku afẹku, ki Ọlọrun maṣe ni tẹle-tẹle.

Aki awọn ẹbi rẹ l'Eko nihin ati awọn ti Abẹokuta nwọn ku oya aiye, ki Oluwa fi mọ bayi, ki o si da awọn ọmọ rẹ si fun iranti anfani oruko rere baba wọn- amin.

Ki Allah gbe si Afẹfẹ rere.

## Irinwo - le-meje Enia F'ara-gbala-mo

GBOKO - Irohin "ti"a" tun ri gbọ lati ilu Gboko ni wipe ọwọ ọlọpa tun tẹ irinwo ẹnia o le mej- fun ẹsun jagidi-jagan ni agbegbe Tiv, ninu rogbodiyan ti o nja ranyin nilu na nisisiyi.

Nigbati nwọn mu awọn ọdaran na de iwaju adajọ, nwọn ṣe idajọ bulala mẹfa fun enia kọkan. Awọn enia mejile-lọgọta ti nwọn jẹ agbalagba ti nwọn fi sun ẹsun kanna ni adajọ bu owo pọnun marun-marun fun ni sisan tabi ẹwọn osu kọkan.

Awọn ọdomode mejidi-ladọta ni adajọ ṣe ikilọ fun, ti o si da wọn silẹ. Awọn enia mokanle-lọgọfa miran ni nwọn da lẹbi atenabole, Ole-jija ati fifo ile onile ninu rogbodiyan na.

## Awon Omo Nigeria To Nkose Ninu Oko Oju omi



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn omo ilẹ Nigeria ati ọmọ ilu Saro kan ti nwon ran lo ko ise ninu oko Oju-omi, Okọ ẹru ti nwọn npe ni Sulima ti awọn Oyinbo Ọlọkọ Oju-omi Elder Dempster Lines Ltd) yi pada si ọkọ ti nwọn yio ma fi kọ iṣẹ.

Awọn omo akọko na ni nwọn nko niṣe lati le fi ṣiṣẹ fun awọn Oyinbo Elebute (Nig: Port Authority). Oruko wọn lati owo osi niwọnyi: B A. Anyaeji E A. Akalonu Oga'ko I. A. C. Logan E. E. Nzewi, Captain I. Sznage, B. E. Nzurumike ati K. K. Laniyan.

Lehin ti won ba fi ọdun mesan kọṣẹ lori okun ni gbogbo wọn yio to gba'we ẹri (Masters Certificate) pe nwọn ti d'ọga ninu ọkọ Oju-omi.

# Oga Ile Onje Yaba F'ara-korin

YABA - L'ojo Alamisi (Thursday) ọsẹ yi ni awọn ọlọpa mu ẹjọ Ọgbeni Jamil Khoury, Ọga ile onjẹ (Hotel Manager) ni Yaba Ebutemetta wa siwaju adajọ fun ẹsun wipe o ṣe idiwọ fun ọlọpa lati ṣiṣẹ wọn, o si fa iwe ipa (Warrant) ti awọn ọlọpa fẹ fi ṣiṣẹ ya, ni ile onjẹ ti nwọn npe ni Ambassador loru ọjọ kejọ oṣu May, ọdun yi.

Adajọ sọ ninu ọrọ idajọ rẹ pe ọdaran yi, ti o jẹ ẹniti o wa ni ipo pataki, ti ṣe aidara pupọ fun awọn enia nipa gbigba awọn ṣaṣawẹrẹ laye faaji inu ile onjẹ, ti ko si jẹki nwọn r'aye mu wọn.

Adajọ sọ wipe on gba pe ọdaran na f'awe ipa (Search warrant) ya, ki nwọn ma ba le yẹ ile onjẹ rẹ wo lati mu wọn ati pe o ja awọn ṣaṣawẹrẹ ọmọ obinrin meji ti nwọn ti mu ni iṣiwaju gba mọ awọn ọlọpa lọwọ. Nitorina ki o lọ san adọta pọnun tabi ẹwọn oṣu mẹrin pẹlu iṣẹ aṣe-la'gun.

---

ẸNITI O GBADAMỌDI OYE IWE MIMỌ

(O bere loju ewe kini)

wọṣẹ olukọ awọn ọmọ ilewe giga nilu Ibadan, St. Theresa's College, Ibadan.

Awọn ọlọpa sọ wipe Vincent kọwe fun iṣẹ olukọ ( Teacher ) ninu ilewe giga St. Theresa College, o si kọ sinu iwe iwaṣẹ rẹ pe on ti gba oye iwe mimọ bi "B. A., M. A., ati PH.D." nipa bẹ, nwọn gba si iṣẹ, nwọn si fi si ipo olukọ agba ni ọjọ kini oṣu July, 1960, nwọn nsan £114:10/- losoṣu fun u.

Ṣugbọn lẹhin oṣu keji ti o ti gba owo iṣẹ rẹ ni aṣiri wa tu s'epo ti Sister Melda wa ri wipe opurọ ni, ko gba oye rara. Nigbati nwọn ṣe abere ẹhin wo lọwọ rẹ, ṣe "Okobo ko nbimọ si tosi", o sọ pe iwe ẹri oye ti on gba wa lọdọ Olotu ilewe giga ti ilu Nsukka. Adajọ ni ki o lọ s'ẹwọn ọdun meji.


M. B. T.

(MAGIC BLOOD TONIC)



Ina dẹ, ọkunkun paradà. M.B.T dẹ, ọkunrun ṣọ lọ. Ẹjẹ dudu sárẹ ọyi pọsẹjẹ. Ala buburu wọ gba ọilẹsun rẹhin-ẹkun. M.B.T. rọgun ẹjẹ ti nmu ni jẹun b'ikan, amu ni yagbẹ bi ọkun, amu ni lọ bi ọkẹrẹ. Abiwẹrẹ f'abuyun, agbẹjẹdi f'awọn abiyamọ. Ahọn-dudu, ẹsẹ wiwu ati aiya-jijá ko si pẹnikl nlo o. 6/6 pẹlu 1/6 owo-ọkọ.

ARADAN STORES P.O.Box 2 EBUTE-METTA.



# "CEMENT"




BSS. 12/1958

THE STRONGEST OF ALL

IT'S NIGERIAN PRODUCT OF HIGHEST QUALITY FRESH FROM IT'S FACTORY

EWEKORO WORKS

MILE 40, ABEOKUTA ROAD.

You Will Be Able To Obtain Supplies Of This Highest Quality Cement From:-

MESSRS BREWACO (NIGERIA) TRADING CO.

11, Martins Street (3rd Floor)
P. O. Box 447 Telephone 25627,
LAGOS, NIGERIA.

Please Telephone, Call or Write Us In Order To Avoid Disappointment


Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, P. O. Box, 467, Lagos, Phone 23??

# Iwa Iyara-Eni Soto Nkase Nile America

NEW - YORK. Irohin ta siwa leti lati ile America wa pe awon enia funfun ati enia dudu ni yio lijo ma joko po jeun lori Tabili kanna ninu awon ilu mejila-logofa ti o mbe ni iha Gusu ile Amarica.

Ninu itode ti awon ilu merenin ti o je pataki se ni wipe awon ti jigiri si ayipada rere ti o ngele nile Amerika, nitorina, iya enia soto ko ni si mo.

# Oloye Awolowo Fi Ipale Sosi St. Saviour Lele

Lojo Ose tokoja ni Oloye Obafemi Awolowo, ti ise asiwaju Ijo Alatako ninu ile igbimo Apapose, fi ipale ile isin St. Saviour ti ilu Ikenne lele. Owo ti nwon yio fi ko ile isin na yio to egba merinla ponun. ( £ 28, 000 ).

Nwon fi okuta ipale ile isin na se iranti Oloye Awolowo gegebi eniti o ko j'oye Olotu ijoba ipinle Iwo-orun, Ile Nigeria ati ise rere re ti o fi se iranlowo ilosiwaju ile isin ti baba ti o bi Oloye Awolowo je asiwaju ninu sosi na.



Awon enia jankan-jankan ti o peju pese si bi isin ojo na ni Olotu ijoba Iwo-orun, Oloye S. L. Akintola ati iyawo re, awon Oba pataki-pataki ati awon Ijoye jako-jado ile Ijebu. Olori Alufa ti ilu Eko, Eni-owo A. W. Howells ni o se akanse isin lojo na.

Awon ore ( Donations ) ti nwon ri gba nibi isin ojo na to ededegbejo ponun ( £ 1,500 ), nibe ni Gomina Iwo-orun, Olola nla Sir Adesoji Aderemi, Olotu ijoba Iwo-orun, Oloye S. L. Akintola ati Oloye Obafemi Awolowo, ni eni kokan won fi ponun marun-le-logorun ta ile isin na lore.

Oloye Awolowo ti o je omo ibile ilu Ikenne ti fi owo bi egberun-le-irinwo ponun ta ile isin na lore ki a tun fi adota-le-rugba ponun ti iyawo re fi ta Sosi na lore kun. Awon Ijo ni ireti pe kiko ile isin na yio pari ninu osu December, 1960.

Olorun feran awon to ntore anu, apo yin ko ni gbe o.

## Eniti O Puro Fun Olopa Dewaju Adajo

Gboko. Akowe ile ise ijoba ibile kan nilu Gboko, ti nwon npe oruko re ni Akpe Sue ni awon olopa mu wa siwaju adajo fun esun pe o wa puro fun olopa.

Awon olopa so niwaju adajo wipe ni ojo kerinla osu September ni Sue wa jafafa fun awon olopa wipe eni die ninu awon alatilehin egbe U. M. B. C. dapomo Action Group ti nwon tina bole onile ti nwon si nko eru inu awon ile na.

Nigbati awon olopa gbo oro yi, nwon bere si se iwadi, nigbehin-gbehin ni nwon to ti pe oro funfun bolau l'owa pa fun won. Ogbeni Sue ni on ko jebi, adajo fi gbigbo ejo na si ojo kejilelogun osu October, 1960.

Ibile ilu Ibini nigbati nwon dibo lati yan eniti yio je Alaga igbimo fun odun 1961 - 62, ti ibo ti nwon di na f'ore fun Ogbeni M I Agbotan ti o si ja enikeji re Ogbeni F.Y Eke kule lori Ogoji ibo si mokanle-logbon ( 40 - 31 ).

Ki a to mase gbagbe pe Ogbeni F.Y. Eke ni o ni o ti j'oye Alaga Igbimo na lati odun to koja. Nigbati nkan na je bayi, lesekanna ni Ogbeni Eke fi iwe iyowo-yose kuro ninu igbimo ati ninu egbe Afenifere (A. G.) siwaju Igbimo.

Awon Oloye meji tun f'iwe ti won na siwaju igbimo pe awon na yo kuro ninu igbimo nitori ibo ti nwon di na.

## Ipade Igbimo Benin Di Rogbodiyan

BENIN - Rogbodiyan be sile ninu ipade Igbimo

## Iku Doro, Ramonu Atanda Do'logbe

EKO. Pelu ibanuje ni a a fi se irohin iku Abudu Ramonu Atanda Idowu Animawun, ti o s'alaisi ninu ile re ni adugbo Onikepo Street, l'Eko ni ojo 18th osu October ti a sinku re ni ojo 19th Osu October, 1960.

(Wo yoku loju ewe keje)

# AWON TO LO KOSE ERO ALAWORAN



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn meji ti Ijọba Iwọ-orun ran lọ kọ iṣẹ Ẹrọ Alaworan nilu Oyinbo.
Awọn ni a nwo ninu ile iṣẹ Ẹrọ Alaworan (Television) ti nwọn nṣe ayẹwo awọn ẹrọ ti nwọn fẹ fi ranṣẹ silẹ Nigeria.

## Owo L'obinrin Mo.

(Apa keji)

Ki a ma d'ena-p'ẹnu, asiko to ni ọjọ keji ti Adejumọ ti iṣe ọrẹ kori-kosun ọkọ iyawo ni lati lọ bẹ iyawo ọrẹ rẹ wo, ki o si le ṣika alukawani rẹ boya yio bọsi ki o le gba owo pọnun meji lọwọ ọrẹ rẹ, Ọlaifa.

Ki ẹ ma gbagbe wipe o ti fun iyawo yi ni ṣile marun (5/-) ni akọkọ, nigbati nwọn ṣe adehun o tun lọ wa owo bi ṣile mẹdogun (15/-) o ko sinu apo ṣokoto rẹ, o dorikọ ọna ile ọdọ iyawo ọrẹ rẹ. Nigbati o ti yọ ni okere ti o mbọ ni iyawo ti nṣe iyẹsi rẹ nipa kiki mẹsan-mẹwa bayi wipe; ẹ ma wo'lẹ, ẹ ma rọra.

"Ako ni ba opo lọ sile oloro mọ," nitoripe bi a ba wipe "mọ ọ" gbogbo ẹnyin ọmọran ni yio ti mọ Adejumọ de'bẹ, ere ni awada ni, kalamu wọnu tadawa, tabi kilo tun ku? Aṣamọṣamọ, Adejumọ ti nro inu ara rẹ pe kini on le fi jẹri ti ọkọ obinrin na ti o jẹ ọrẹ on yio fi ni igbagbọ wipe otitọ ni on fun iyawo rẹ ni ife oyin-ara kan mu, ti o si mu ni amu gbadun.

Nigbati nwọn wa ni faaji, o ranti wipe iyawo yi ni Ikoti kan to ma fi nha irun ori rẹ, o si ma nsaba fi ikoti na ko eri eti fun ọkọ rẹ, o wa d'ọgbọn yọ ikoti na kuro lori iyawo, o fi pamọ lati fi ṣe ẹlẹri. Nigbati ọwọ rẹ ti tẹ ohun ti o nfẹ, o dide, o sọ fun iyawo pe on fẹ tete lọ nitoripe awọn ni nkan pataki lati ṣe nil . O tọwọ bọ apo ṣokoto rẹ, o si ko owo to wa nibẹ jade, o ka, o jẹ ṣile mẹdogun, o si ko gbogbo owo na fun iyawo. Iyawo dupẹ, o tun ọpẹ da.

Lọjọ keji ni ọkọ iyawo, Ọlaifa ti o jẹ ọrẹ Adejumọ ti idalẹ ti o ti lọ de o wọle, iyawo rẹ ki i tayọtayọ ọkọ na wa pe ọmọ rẹ, o ni ki o lọ sọ fun ọrẹ on Adejumọ pe o n ti de o.

Nigbati ọmọ lọ tan ni iyawo bẹrẹ si rohin ọrẹ rẹ fun wipe ọmọluwabi, enia atata ni ọrẹ rẹ na, lati ijọ ti o ti lọ, ko jẹ ki nwa nkan-kan ti, t'owo-towo l'o fi nkẹ mi, nitori na ki o dupẹ fun ọrẹ rẹ na dara-dara.

Nipa gbolohun ọrọ ti iyawo nsọ yi, ara ti bẹrẹ si fu ọkọ, ṣe iyawo ko mọ wipe nwọn ni adehun ki ọkọ on to lọ si idalẹ.

Loku di ọsẹ ti o mbọ lagbara Edumare.

## Egbe Afenifere (Action Group) Eka Ti Mushin Yan Awon Osise Egbe

MUSHIN - Ẹgbẹ Afẹnifere (A.G.) ẹka ti Mushin ṣe ipade kan lọjọ Satide to koja 15th oṣu yi, lati yan awọn oṣiṣẹ ẹgbẹ ati awọn ọgbọn (30) enia ti yio jẹ alaṣaro ọrọ ẹgbẹ ninu Gbọngan Igbimọ Ibilẹ ti Mushin.

Abiyẹluwa Oba Onisolo ti Ilu Ikọlo ni Ibiba'sule Ogbeni S.A. Onitiri ni Alaga ipade na, Oloye S.O. Gbadamọsi Alaga ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa Mushin, Oloye V. Ade. Cole, Balẹ Aiyetoro, Iyafin Ọmọwunmi ati Ogbẹni F.O. Akintọla, awọn ni enia pataki ti o ṣe isọngbe Alaga ipade na.

Awọn enia ti ayan na nwọnyi:-

Ogbẹni J. S. Ọdẹtọla
Alaga Ẹgbẹ

Oloye Lawal Ẹkerin
Igbakeji Alaga

Ọgbẹni M. A. Labinjọ
Akọwe ẹgbẹ

A. Onilẹgbalẹ
Igbakeji Akọwe.

Alufa S. A. Ọṣọba
Akọwe-owo ẹgbẹ

Iyafin E. O. Labinjo
Akọwe Irohin ẹgbẹ.

Ogbẹni J. A. Ọnasanya
Igbakeji Akọwe Irohin ẹgbẹ

Ogbẹni S. M. Welkey
Akapo-owo ẹgbẹ

Imam Abiọla Ishọla
Alayẹwo Iwe-owo ẹgbẹ

Gbogbo igbimọ titun ti a yan l'o ni igbẹkẹle si ẹgbẹ ati aṣiwaju ẹgbẹ, nwọn si ṣe ipinnu lati ṣiṣẹ fun ilọsiwaju ati idagbasoke ẹgbẹ nilu Mushin.

E. O. Labinjo
Akọwe Irohin Ẹgbẹ

# ELETI - OFE

ANJUWON KO ȘE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI — OFE, LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XII. NO. 698. SATURDAY OCT. 22, - OCT. 28, 1960


## IWA IMELE KO DARA !

Gegebi a ti gba Ominira ilẹ wa Nigeria yi, o tọ, o si yẹ ki olukuluku awọn oṣiṣẹ, yala ni oṣiṣẹ ijọba tabi oṣiṣẹ ilu tabi oṣiṣẹ awọn Onișowo, Onișẹ ọwọ tabi akọwe ti o fi kan awọn Lebira tabi Afọgọta wipe ki a maṣe ṣe imẹlẹ ninu iṣẹ wa, nitoripe iṣẹ imẹlẹ ko le gbe ilu ga, bi enia ba si nṣe imẹlẹ ninu iṣẹ rẹ nilu rẹ ti o ṣẹṣẹ gba Ominira, ara oluwarẹ ati ilu rẹ ni ẹnibẹ nṣe ni aidara.

Nitoripe Ominira ki iṣe ohun ti a ni lati fi ṣe imẹlẹ iṣẹ bi koṣe wipe ki a tẹ ṣokoto wabọ giri, ki a fi gbogbo agbara wa ṣe iṣẹ ti Oluwa ba pese fun Olukuluku wa pẹlu ifẹ atọkanwa fun ire ilọsiwaju ati idagbasoke ilu wa ọwọn yi, ti o di ọkan ninu awọn Orile-ede agbaiye.

Ọpọ'ọpọ awọn ọmọ wa ti nwọn ti lọ silu awọn Oyinbo, awọn ti o kọ wa l'ẹkọ ti nwọn fi ọna han wa, bi a ti nṣe di enia pataki ti ilu wa yio sile duro ṣinṣin l'awujọ awọn orilẹ-ede, ni nwọn fi ye wa wipe bi enia ba ri awọn Oyinbo nibi ti nwọn nṣe iṣẹ nilu wọn, yio ya ni lẹnu pe lasiko si ẹniti o nṣọ wọn, olukuluku nu yio ma fi t'ara-t'ọkan ṣ'iṣẹ rẹ bi o ti tọ ati bi o ti yẹ.

Njẹ ẹnyin ara, ẹ jẹki a fi iwa aișemẹlẹ awọn olukọ wa Oyinbo wọnyi kun ẹkọ wa, ki o le ri fun wa gegebi o ti ri fun wọn.


## OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ṢE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

**E Polowo Oja Yin**
**Sinnu Iwe Irohin**
**ELETI-OFE**


## WA WI TENU RE

IBADAN - Ile ẹjọ giga tilu Ibadan ni nwọn ti m'ẹnu kan ẹrọ ẹjọ ti Ẹgbẹ Alatako (N.C.N.C). ti o wa nilẹ Iwọ-Orun pe Gomina ati Alabojuto Ijọba Iwọ-Orun lori ile igbimọ ibilẹ ti ilu Ilesha ti Ijọba Iwọ-Orun tuka lori aiṣe dede awọn Olugbimọ na.

Adajọ agba Ọgbẹni S. O. Quashie - Idun pașẹ wipe ki awọn ti o pe ẹjọ ati awọn ti nwọn pe lẹjọ lọ ro'jọ wọn sinu iwe ki nwọn o mu wa si kotu larin ọjọ mọkanle-logun, o si yẹ riro ẹjọ na si ọjọ kejila oṣu December, 1960.

Ohun ti a gbọ wipe o da rogbodiyan yi sile niti ipinnu ti awọn Olugbimọ ṣe le Alaiyeluwa Ọba Ogunmokun Biladu III Ọwa ilẹ Ilẹsha lori wipe ki o fi ori ite Ọba rẹ silẹ, ti Ijọba Iwọ-Orun sọ wipe ede na ko bakungbe rara, ati pe o jẹ ede abuku si Ọba ori-ite. Nitorina ki nwọn kojẹ, ti nwọn kọ lati kojẹ, eyi l'o mu Ijọba da seria fun wọn nipa titu igbimọ ibilẹ na ka.

## OMO NIGERIA TO KOSE ERO



Aworan ti a nwo yi niti ọmọ ilẹ Nigeria ti o lọ koṣẹ ẹrọ nilu Oyinbo. Ibiti nwọn ti nkọ iṣẹ ẹrọ na ni ile iṣẹ ẹrọ kan ti nwọn npe ni Loughborough College of Technology, ti o mbẹ larin ilu England, nibẹ ni gbogbo ọmọ ikọṣẹ kakiri agbaiye ti ma nlọ kọ iṣẹ ẹrọ lorișiriși, ẹrọ ti ọkọ ilẹ ati ti oju-omi, ti mọto ati Ina mọnamọna.

Ọbẹni D. A. O. Amao ti ilu Iwọ-orun Nigeria ni o nṣe ayẹwo ẹrọ ti a nwo ninu aworan yi.

## Convicted For Cruelty To A Cow

Last week-end at Magistrate's Court NO. 5, Lasisi Ayiki, who pleaded guilty to a charge of cruelty to a cow was fined £2 with an option of one month imprisonment for beating a cow to death. The accused was taking a cow from Apapa to Mushin where the cow was to be slaughtered. He was caught on the road by an R. S. P. C. A. member while mercilessly beating the animal without any reasonable excuse. An R. S. P. C. A. Inspector was immediately detailed to see the complaint. The accused was later reported to the Police. The cow later died and a post mortem was performed.

## Nawair - Ud-Deen Elects New Officers

Recently, the annual election of the Young Nawairud - Deen Society Lagos Branch took place and in his annual report, the Secretary of the Soceity Mr. R.A. Bello who was later returned made mention of the important parts the voluntary organisations are playing in the Development of our great country particularly in the field of education. He called on his members to rededicate themselves to the task ahead so that the society may proudly take its due honour as one of the builders of of our free nations.

Other officers elected were Alhaji R.B. Idowu Chairman, Alhaji A.R.A. Makọnjuọla Vice - Chairman, R. I. Hassan 1st Assistant Secretary, L. O. Obikọya 2nd Assistant Secretary, S.A. Adenẹkan Treasurer, M. O. Busari Financial Secretary, R.A. Akindele Asistant Financial Secretary A. O. Ọlabọde Sectetary Mission Board B. Salawu Assistant Mission Board Secretary any Messrs B.A. Yussuff and M.O. Baruwa Joint Auditors.

# BABA EGBE IJOBA AMERIKA ATI OLOTU IJOBA GESI



Ọgbẹni Eisenhower ti iṣe Baba Ẹgbẹ Ijọba (President) ilẹ America, ati Ọgbẹni Harold Macmillan, Olotu Ijọba Gẹsi (Prime Minister) ni a nwo ninu aworan yi nigbati Ọgbẹni Eisenhower wa silu Oyinbo Gẹsi fun ajọsọ ọrọ.

Ọgbẹni Eisenhower pẹlu Ọgbẹni Macmillan ni awọn mejeji jọ lọ ṣe isin owurọ ninu Ṣọṣi St. Peter ati St. Paul ni Ellesborough.